# Kí ni Kuraani Alapọn-ọnle?



Kuraani Alapọn-ọnle ni ọ̀rọ̀ Ọlọ́hun, Oluwa gbogbo agbaye ati Ẹlẹ́dàá wọn, O sọ Kuraani yii kalẹ fun ẹniti o gbẹhin ninu awọn Anabi ati awọn Ojiṣẹ, Muhammad - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - lati le ṣalaye fun awọn eniyan idi ti wọn tori rẹ ṣẹda wọn, ati lati le ṣe ìmọ̀nà fun wọn lọ si ibi ohun ti yoo mu wọn dunnu ni aye ati ọjọ ikẹyin, ati lati le yọ wọn kuro ninu ibanujẹ ayeraye lẹhin iku. Ati pe Kuraani yii jẹ tira to gbẹhin sọkalẹ ninu awọn tira Ọlọhun, ti o n pe awọn tira to ṣiwaju rẹ lododo, ti o si n pa àwọn ofin inu wọn rẹ́.

Kuraani Alapọn-ọnle jẹ àmì ati iṣẹ́ ìyanu ti gbere, oun si ni ẹri lórí ijẹ anọbi ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- Ọlọhun fi pe àwọn ènìyàn àti àwọn alujannu nija láti mu irú rẹ wa, kódà ko jẹ suura kan péré nínú rẹ, wọn ko si le mu u wa.

Ọwọ ìyípadà kò kan Kuraani ri, lati igba ti o ti sọ̀kalẹ̀ ni nǹkan to le ni 1400 ọdun sẹyin, yoo si maa wa ni nnkan ti a da aabo bo pẹlu ede Larubawa ti o sọ̀kalẹ̀ pẹlu rẹ̀, nitori pe Ọlọhun Ọba ti ṣe idaniloju ìdáàbòbò rẹ̀ titi di igbẹhin igba.

Kuraani Alapọn-ọnle ni orisun ìpìlẹ̀ fun Islam, oun sì ni iwe ofin tí ó n ṣeto, tí ó sì n ṣakoso igbesi aye eniyan ni gbogbo igba ati aaye, o n pepe lọ sibi ijọsin fun Ọlọhun Ẹlẹdaa nikan ṣoṣo, o sì n ṣalaye ohun ti eniyan nílò láti mọ nipa Oluwa rẹ̀ ati ẹsin rẹ̀, ati ibẹrẹ ṣiṣẹda àgbáyé, ati awọn ipele ṣiṣẹda eniyan, o sì n fun wa ni iro nípa awọn ìṣẹ̀lẹ̀ ìkọ̀kọ̀ ti o ti lọ àti eyi ti o si maa ṣẹlẹ̀, àti nípa ìtàn àwọn Ànábì ti wọn saaju – àlàáfià fun wọn – ati bí Ọlọ́hun ṣe ràn wọ́n lọ́wọ́, tí Ó sì pa àwọn ọ̀tá wọn run, ati pe o wa ninu Kuraani yii, awọn ìpìlẹ̀ ijọsin ati ibara-ẹni-lopọ, ati ipepe lọ sibi awọn iwa daada, ati ṣiṣọnilara kuro nibi awọn iwa ti ko dara, ati ibupadasi ẹda ni ọrun; bóyá Al-jannah ni, ti o jẹ ile awọn onigbagbọ ododo, tabi Ina, ti o jẹ ile awọn alabosi ati awọn alaigbagbọ.

Fún ṣíṣe pàtàkì tira nla yii, eyi ti Ọlọhun sọkalẹ pẹ̀lú èdè Lárúbáwá, ti O si pàṣẹ lati mu u de etigbọọ àwọn èèyàn, yoo dun mọ wa- ìwọ olùkà alapọn-ọnle- lati ti síwájú fun ẹ itumọ rẹ si èdè mìíràn pẹlu èdè rẹ, lati le jẹ ki o rọrùn lati gbọye, ati lati le mu u de etigbọọ àwọn èèyàn. Àwọn ikọ̀ iṣẹ ti gbiyànjú lati gbọ itumọ rẹ ye, ati lati tu u si èdè mìíràn, pẹ̀lú amọdaju pe ko si bi itumọ rẹ si èdè mìíràn ba ṣe bọ́ sójú ẹ to, ko lee pe àwọn ìtumọ̀ ńlá ti ọrọ Kuraani ti n kagara bani n tọ́ka si, èyí tí o tayọ iṣẹ́ ẹ̀dá abara. Ẹni tí ó ba fẹ mọ síi nipa àwọn òtítọ́ ti Kuraani Alapọn-ọnle mu wa, a n gba a ni ìmọ̀ràn lati lọ kọ́ èdè Lárúbáwá ti o sọkalẹ pẹ̀lú ẹ.

Alaafia fun gbogbo awọn Ojiṣẹ Ọlọhun, ọpẹ ni fun Allah, Oluwa gbogbo agbaye.

**Agbedegbẹyọ Kuraani Alapọn-ọnle**

O lè wo àwọn ìtumọ̀ Kuraani Alapọn-ọnle pẹ̀lú èdè rẹ nípa ṣíṣẹ̀dà àwòrán koodu ti o hàn naa (QR Code) pẹ̀lú kámẹ́rà fóònù.

Inu wa a dun lati gba awọn àbá ati akiyesi yin fun idagbasoke itumọ si èdè mìíràn yii, nipasẹ ferese awọn akiyesi ti o wa ni iwaju aayah kọọkan lori oju opo wẹẹbu agbedegbẹyọ Kuraani Alapọn-ọnle

**(www.quranenc.com)**

ati pé tí ó ba wù yin lati kàn si wa, ẹ le fi atẹjiṣẹ ranṣẹ si wa nípasẹ̀ imeeli yii:

**info@quranenc.com**

موسوعة القرآن الكريم
QuranEnc.com